Dajudaju wọn n jẹ awọn mejeeji niya lọwọ, wọn o si jẹ wọn niya nitori alamọri nla kan (ni iwoyesi awọn eeyan), ẹ o wa ri ọkan ninu awọn mejeeji o jẹ ẹni ti kii mọra kuro nibi itọ, amọ ẹnìkejì o jẹ ẹni ti maa n gbé ọrọ ofofo kaakiri

Lati ọdọ ọmọ Abbās - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji - o sọ pe: Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - kọja nibi saare meji kan, ni o wa sọ pe: «Dajudaju wọn n jẹ awọn mejeeji niya lọwọ, wọn o si jẹ wọn niya nitori alamọri nla kan (ni iwoyesi awọn eeyan), ẹ o wa ri ọkan ninu awọn mejeeji o jẹ ẹni ti kii mọra kuro nibi itọ, amọ ẹnìkejì o jẹ ẹni ti maa n gbé ọrọ ofofo kaakiri» lẹyin naa ni o wa mu imọ ọpẹ tutu o si ya a si meji, ti o si tun ri ẹyọ kọọkan mọ saare kọọkan, wọn wa sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ki ni idi ti o fi ṣe eleyii? O sọ pe: «O ṣee ṣe ki wọn o ṣe iya awọn mejeeji ni fufuyẹ lopin igba ti wọn o ba tii gbẹ (imọ ọpẹ)».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - kọja nibi saare meji kan, ni o wa sọ pe: Dajudaju awọn meji ti wọn ni saare mejeeji yii wọn n jẹ wọn niya lọwọ; ati pe wọn o jẹ wọn niya lori alamọri ti o tobi ni iwoyesi yin, bi o tilẹ jẹ pé o tobi lọdọ Ọlọhun, Ẹ o wa ri ọkan ninu awọn mejeeji o jẹ ẹni ti ko ni akolekan nipa ṣiṣọ ara rẹ ati aṣọ rẹ kuro nibi itọ nigba ti o ba n gbọ bukaata rẹ, Ati pe ikeji maa n ṣe ofofo laarin awọn eeyan, ti yio wa maa gbe ọrọ ẹni ti o yatọ si i ni erongba ifi-ara-ni ati dida iyapa ati ogun silẹ laarin awọn eeyan.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3010

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee